# Lẹ́yìn abẹ́rẹ́-àjẹsára Comir-naty (Pfizer / BioNTech ) fún COVID-19 rẹ

O ṣeun fún dídáàbòbo ara rẹ ati awọn miran nipa gbigba abẹ́rẹ́-àjẹsára yii. Ní bayii tí o ti gba abẹ́rẹ́-àjẹsára rẹ, a rọ̀ ọ́ kí o ka iwe yii daradara, kí o lè mọ̀ bí ara rẹ yoo ṣe rí laarin awọn ọjọ diẹ ti nbo ati ibití o ti lè gba alaye siwaju si i. Rí i pé o ka iwe pelebe alaye abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19 ti a fun ọ nipa abẹ́rẹ́-àjẹsára naa.

A tun maa fun ọ ni akọsilẹ abẹ́rẹ́-àjẹsára tí o gba lònii. **Jọwọ tọju kaadi akọsilẹ naa daadaa.**

**Kini o le ṣẹlẹ ní awọn ọjọ diẹ ti nbọ?**

Awọn eniyan kan tó gbà abẹ́rẹ́-àjẹsára ti o gbà loni ní awọn imọlara yii:

- ojú ibi ti wọn ti gba abẹ́rẹ́-àjẹsára naa sí apá wọn yoo dẹ̀, yoo wú tabi kí ibẹ̀ pọ́n roro
- rírẹ̀ ara
- ẹfọri
- ìrora inu ẹran-ara
- ìròra oríkèèríkèé ara
- ọkàn rírìn
- àìsàn ibà (ìmóoru bí i 38oC tabi ju bẹẹ lọ).

Fun gbogbo awọn abẹ́rẹ́-àjẹsára, bí o bá fura pé ó gba òdì lọ lara rẹ, jábọ̀ eyi fún Àjọ tí n Ṣàkóso awọn Eroja Ìlera (HPRA).

Lati jábọ̀ bí abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19 naa bá gba òdì lọ lara rẹ, jọwọ kàn sí **www.hpra.ie/report**

**Tí mo bá ní ibà tabi ìrora?**

Tí o bá ní ibà tabi ìrora, o lè lo oogun paracetamol tabi ibuprofen lati ṣeranwọ. Sibẹsibẹ, tí ibà rẹ ba ju ọjọ meji lọ tabi tí ara rẹ kò bá balẹ̀, jọwọ gba imọran lọdọ onişẹ ilera. Maṣe lo ibuprofen tí o bá loyún.

**Njẹ ohun kan n bẹ fun mi lati ṣe kí n tó lè gba abẹ́rẹ́-àjẹsára ẹlẹẹkeji bi?**

Nigbati o ba n gba abẹ́rẹ́-àjẹsára tó kàn ati eyi tó kẹyin, jọwọ sọ fun ikọ̀ alabẹ́rẹ́-àjẹsára bí awọn ayipada kan ba ti waye ninu akọsilẹ itọju ilera rẹ.

**Mu kaadi akọsilẹ abẹ́rẹ́-àjẹsára rẹ lọwọ nigba ti o bá fẹ́ gba ẹlẹẹkeji.**

Eyi yoo jẹ ọjọ mejidinlọgbọn (ọsẹ mẹrin) sí àkókò yii.

**Iroyin ayọ**

Gbigba abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19 yoo daabobo ọ kuro lọwọ lati awọn àkóbá tí COVID-19 n ṣe fun ara.

Awọn abẹ́rẹ́-àjẹsára n kọ awọn ọlọpaa agọ ara rẹ lati daabobo ọ lọwọ awọn aisan. Ó dára pupọ kí awọn ọlọpaa agọ ara rẹ kẹkọọ yii nipasẹ abẹ́rẹ́-àjẹsára ju kí o kó aisan COVID-19 lọ.

**A sì nkọ ẹkọ lọwọ**

Yoo tó ọjọ meje (7) lẹyin tí o gba abẹ́rẹ́-àjẹsára ẹlẹẹkeji kí ó tó bẹrẹ iṣẹ lara.

Ó sì tún ṣeeṣe diẹ kí o kó aisan COVID-19 biotilẹjẹpe o ti gba abẹ́rẹ́-àjẹsára naa.

- A ko tí ì mọ daju bí gbigba abẹ́rẹ́-àjẹsára kò ní í jẹki o lè tan aisan naa kalẹ, nitorinaa o sì gbọdọ maa tẹle awọn imọran ilera lawujọ:
- tẹle awọn itọnisọna títakété si ẹnikeji lawujọ (fi mita meji silẹ sí ẹlomiran ni awọn ibiti o ti ṣee ṣe)
- lo ìbojúbonu
- máa fọ ọwọ́ rẹ déédéé.

**Ṣe o ní ìbéèrè?**

Ti ohun kan kò bá da ọ loju, tabi o ní ibeere kankan nipa abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19, jọwọ beere lọwọ wa bayii tabi ṣabẹwo sí **hse.ie/covid19vaccine** tabi kí o pè HSELive lori nọmba foonu **1850 24 1850**.

Atẹjade lati ọdọ HSE ní ọjọ kẹrinla
Oṣu Kini ọdun 2021. Ẹ̀dà 3.

Rialtas na hÉireann
Government of Ireland